# Tani o da agbaye? Taa si ni o da mi? Ati pe ki ni idi ti o fi da mi?

شركاء التنفيذ:

ISLAM HOUSE .com

دار الإسلام جمعية الربوة رواد الترجمة المحتوى الإسلامي

يتاح طباعة هذا الإصدار ونشره بأي وسيلة مع
الالتزام بالإشارة إلى المصدر وعدم التغيير في النص.

Telephone: +966114454900
ceo@rabwah.sa
P.O.BOX: 29465
RIYADH: 11557
www.islamhouse.com

# Nję mo wa lori oju ọna ti o tọ̀nà?

Tani o da awọn sanmọ ati ilẹ ati awọn nkan ti o wa nínú mejeeji ninu awọn ẹda ti o tobi ti ìmọ̀ wa o lee gbe gbogbo rẹ tan?

Tani o ṣe eto ti o munadoko yii sinu sanmọ ati ilẹ?

Tani o da ọmọniyan ti o si tun fun un ni ìgbọràn ati irina ati làákàyè ti o si tun ṣe e ni ẹni ti o ni ikapa lati wa awọn imọ ati mímọ awọn ododo?

Tani o ṣe iṣẹ ti o péye dáadáa yii sinu oríkèé ara rẹ, ti o si tun ya aworan rẹ ni aworan ti o daa?

Woye si iṣẹda awọn nkan abẹmi ti o n bẹ ni oríṣirísị, taa ni o ṣẹda wọn pẹlu awọn aworan (irisi) ti ko ni aala?

Bawo ni agbaye nla yii ṣe tò ti o si tun fidi mulẹ pẹlu awọn òfin ti o n de e ni dide to péye lati odún gbọọrọ (bi ọdun ṣe n gori ọdun)?

Taa ni o ṣe agbekalẹ awọn eto ti ndari agbaye yii (Iṣẹmi ati ikú, ibisi ati irẹsi awọn alàáyè, oru ati ọsan, iyipada awọn igba, ati bẹẹ bẹẹ lọ)?

Nję aye yii da ara rẹ bii? Abi o wa lati ibi aisi (Asèdá)? Abi o kan ṣèèṣì maa bẹ ni? Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿أَمۡ خُلِقُواْ مِنۡ غَيۡرِ شَيۡءٍ أَمۡ هُمُ ٱلۡخَٰلِقُونَ ٣٥ أَمۡ خَلَقُواْ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَۚ بَل لَّا يُوقِنُونَ ٣٦﴾

[الطور: 35-36]

Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni? (35) Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀? Rárá o, wọn kò màmọ̀ dájú ni[At-Tūr: 35-36].

Ti o ba wa jẹ pe awa ko da ara wa ti o si soro ki a wa lati ibi aisi tabi eesi, a jẹ wipe ododo ti ko si iyemeji nibẹ ni pe: Dajudaju agbaye yii ko gbọdọ ma ni Oluda ti O tobi ti O ni ikapa, tori pé o soro ki ayé yii o da ara rẹ! Tabi ki o wa lati ibi aisi! Tabi ki o ṣèèṣì wa!

Nitori ki ni ọmọniyan yio ṣe gbagbọ ninu bibẹ awọn nnkan ti ko ri? Gẹgẹ bii: (Mimọ nnkan, ati laakaye ati ẹmi ati awọn ìmọ̀lára ati ifẹ) ṣe ko ki n ṣe nitori pe o ri àwọn oripa wọn ni? Bawo ni ọmọniyan ṣe maa tako bibẹ Ẹni tí Ó dá ile aye ti o tobi yii, ti o si n ri awọn oripa awọn ẹda Rẹ ati iṣẹ Rẹ ati ikẹ Rẹ?!

Ẹni kan ti o ni laakaye ko lee gba wọle layelaye ki wọn sọ fun un pé: Ile yii ti wa lai ṣe pe ẹnikan ni o mọ ọn! Tabi ki wọn sọ fun un pé: Dajudaju aisi oun ni o mu ile yii maa bẹ! Bawo ni awọn eniyan kan ṣe lee gba pe olododo ni ẹni ti o ba n sọ bayii pe: Dajudaju agbaye ti o tobi yii wa laisi Adẹdaa kan? Bawo ni onilaakaye kan ṣe lee gba ki wọn sọ fun oun pé: Dajudaju wiwa ti agbaye wa pẹlu eto ti o munadoko yii ṣèèṣì Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin gbigba Isilaamu rẹ, Kò sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe kongẹ fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

ni?

Gbogbo eyi maa mu wa ja si esi kan, oun ni pe, dajudaju Oluwa kan ti O tobi ti O jẹ Olukapa ti O jẹ Oluṣeto kan n bẹ fun agbaye yìí, ati pe Oun nikan ṣoṣo ni Ẹni ti O ni ẹtọ si ijọsin, ati pe dajudaju gbogbo nnkan ti wọn n jọsin fun yàtọ̀ si I, ijọsin rẹ jẹ ibajẹ, ko lẹtọọ si ki wọn maa jọsin fun un.

# Oluwa Adẹdaa Ọba ti O tobi

Oluwa Adẹdaa Ọkan ṣoṣo kan n bẹ, Oun ni Olukapa Oludari Olupese ti O maa n sọ eniyan di alàáyè ti O si maa n sọ eniyan di oku, Oun ni O ṣẹda ilẹ̀ ti O si tẹri rẹ ba, ti O ṣe e ni nnkan ti o daa fun awọn ẹda Rẹ, Oun ni O ṣẹda sanmọ ati nnkan ti o n bẹ nibẹ ninu awọn ẹda ti wọn tobi, ti O ṣe eto ti o péye yii fun oorun ati òṣùpá ati oru ati ọsan, eyi ti o n tọka si titobi Rẹ.

Oun ni O rọ atẹgun fun wa ti ko si iṣẹmi kan fun wa lai si i, Oun ni O n rọ ojo le wa lori ti O ṣe awọn okun ati awọn odo ni rírọ̀ fun wa, Oun ni O n fun wa ni oúnjẹ ti O si n ṣọ wa nigba ti a si wa ni ọlẹ̀ ninu ikun awọn iya wa laisi agbara kan ti o n bẹ fun wa, Oun ni O n mu ẹjẹ ṣan ninu awọn iṣan wa lati igba ti wọn ti bi wa titi a o fi kú.

# Oluwa Adẹdaa Olupese yii ni Allahu-mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga-

﴿إِنَّ رَبَّكُمُ ٱللَّهُ ٱلَّذِى خَلَقَ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلْأَرْضَ فِى سِتَّةِ أَيَّامٍ ثُمَّ ٱسْتَوَىٰ عَلَى ٱلْعَرْشِ يُغْشِى ٱلَّيْلَ ٱلنَّهَارَ يَطْلُبُهُۥ حَثِيثًا وَٱلشَّمْسَ وَٱلْقَمَرَ وَٱلنُّجُومَ مُسَخَّرَٰتٍۭ بِأَمْرِهِۦٓ ۗ أَلَا لَهُ ٱلْخَلْقُ وَٱلْأَمْرُ ۗ تَبَارَكَ ٱللَّهُ رَبُّ ٱلْعَٰلَمِينَ ٥٤﴾ [الأعراف: 54]

{Dájúdájú Olúwa yín ni Allāhu, Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ fún ọjọ́ mẹ́fà. Lẹ́yìn náà, Ó gúnwà sí orí Ìtẹ́-ọlá. Ó ń fi òru bo ọ̀sán lójú, tí òru ń wá ọ̀sán ní kíákíá. Òòrùn, òṣùpá àti àwọn ìràwọ̀ ni wọ́n ti rọ̀ pẹ̀lú àṣẹ Rẹ̀. Gbọ́! TiRẹ̀ ni ẹ̀dá àti àṣẹ. Ìbùkún ni fún Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá.}[Al-A'raf : 54].

Allahu ni Oluwa Oluda gbogbo nnkan ti o wa ninu agbaye yii ninu nnkan ti a n ri ati ninu nnkan ti a kò ri, ati pe gbogbo nnkan ti o yàtọ̀ si I jẹ ẹda ninu awọn ẹda Rẹ, Oun ni O lẹtọọ si ijọ Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin

gbigba Isilaamu rẹ, Kò sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe kongẹ fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

sin ni Oun nikan ṣoṣo, ati pe a ko gbọdọ jọsin fun nnkan ti o yàtọ̀ si I pẹlu Rẹ, ko si orogun fun Un nibi ijọba Rẹ tabi ṣiṣẹda Rẹ tabi ṣíṣe ètò Rẹ ati ijọsin Rẹ.

Tí a ba gbà pé awọn ọlọhun miiran n bẹ pẹlu Oluwa nínú ẹ, ile aye o ba bajẹ; nitori pe ko lee daa ki ọlọhun meji maa dari àlámọ̀rí ile aye ni asiko kan náà, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿لَوۡ كَانَ فِيهِمَآ ءَالِهَةٌ إِلَّا ٱللَّهُ لَفَسَدَتَاۚ ...﴾ [الأنبياء: 22]

(Tí ó bá jẹ́ pé àwọn ọlọ́hun kan wà nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀ lẹ́yìn Allāhu, sánmọ̀ àti ilẹ̀ ìbá ti bàjẹ́)Al-Anbiya' : 22.

# Awọn iroyin Oluwa Adẹdaa

Awọn orukọ ti wọn rẹwa n bẹ fun Oluwa- mimọ ni fun Un- eyi ti ko ṣee ka, awọn iroyin ti wọn ga ti wọn pọ ti wọn tobi n bẹ fun Un eyi ti wọn n da lori pipe Rẹ, ninu awọn orukọ Rẹ ni: Adẹdaa, "Allahu" ìtumọ̀ rẹ ni: Ẹni ti a n sìn ti O lẹtọọ si ijọsin ni Oun nikan ṣoṣo ti ko si orogun fun Un. Ọba Alaaye, Alámòjúútó-ẹ̀dá, Aṣakẹ-ọrun, Olupese ati Ọlọrẹ,

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ ninu Al-Kuraani Alapọn-ọnle pé:

﴿ٱللَّهُ لَآ إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ٱلۡحَيُّ ٱلۡقَيُّومُۚ لَا تَأۡخُذُهُۥ سِنَةٞ وَلَا نَوۡمٞۚ لَّهُۥ مَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَمَا فِي ٱلۡأَرۡضِۗ مَن ذَا ٱلَّذِي يَشۡفَعُ عِندَهُۥٓ إِلَّا بِإِذۡنِهِۦۚ يَعۡلَمُ مَا بَيۡنَ أَيۡدِيهِمۡ وَمَا خَلۡفَهُمۡۖ وَلَا يُحِيطُونَ بِشَيۡءٖ مِّنۡ عِلۡمِهِۦٓ إِلَّا بِمَا شَآءَۚ وَسِعَ كُرۡسِيُّهُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَۖ وَلَا يَـُٔودُهُۥ حِفۡظُهُمَاۚ وَهُوَ ٱلۡعَلِيُّ ٱلۡعَظِيمُ٢٥٥﴾ [البقرة: 255]

(Allāhu, kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alààyè, Alámòjúútó-ẹ̀dá. Òògbé kì í ta Á. Àti pé oorun kì í kùn Ún. TiRẹ̀ ni ohunkóhun t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t'ó wà nínú ilẹ̀. Ta ni ẹni tí ó máa ṣìpẹ̀ lọ́dọ̀ Rẹ̀ àfi pẹ̀lú ìyọ̀ǹda Rẹ̀? Ó mọ ohun tí ń bẹ níwájú wọn àti ohun tí ń bẹ lẹ́yìn wọn. Wọn kò sì ní ìmọ̀ àmọ̀tán nípa kiní kan nínú ìmọ̀ Rẹ̀ àfi ohun tí Ó bá fẹ́ (fi mọ̀ wọ́n). Àga Rẹ̀ gbààyè ju àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ṣíṣọ́ sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò sì dá A lágara. Allāhu ga, Ó tóbi)[Al-Baqarah : 255].

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- tun sọ pe:

﴿قُلْ هُوَ ٱللَّهُ أَحَدٌ ۝١ ٱللَّهُ ٱلصَّمَدُ ۝٢ لَمْ يَلِدْ وَلَمْ يُولَدْ ۝٣ وَلَمْ يَكُن لَّهُۥ كُفُوًا أَحَدٌۢ ۝٤﴾ [الإخلاص:
1-4]

(Sọ pé: "Òun ni Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo (1) Allāhu ni Aṣíwájú (tí ẹ̀dá ní bùkátà sí, tí Òun kò sì ní bùkátà sí wọn (2) Kò bímọ. Wọn kò sì bí I (Kò sì sí ẹnì kan tí ó jọ Ọ́."[Al-Ikhlass 1-4].

# Oluwa Ọba ti a n jọsin fun jẹ́ Ẹniti O ni awọn iroyin pipe

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe Oun ni Ẹni ti a n jọsin fun, ati pe nnkan ti o yàtọ̀ si I jẹ nnkan ti a da, ti a la iwọ bọ lọrun, ti a n pa láṣẹ, ti a borí.

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe, dajudaju Ọba Alaaye, Alámòjúútó-ẹ̀dá ni, ati pe gbogbo alaaye ti n bẹ, Allahu ni Ẹni ti O ye wọn ti O si mu wọn bẹ latara aisi, Oun ni O moju to wọn pẹlu bibẹ Rẹ ati ipese Rẹ ati tito Rẹ. Ati pe Oluwa naa jẹ alaaye ti ko nii ku, ti titan si jẹ kò ṣeé ṣe fun Un, Alamojuuto ti ko ki n sun, koda oogbe tabi oorun kan ko lee gba A mu.

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe Oun ni Ọba Onimimọ ti nnkankan ko pamọ fun Un lori ilẹ tabi ninu sanmọ,

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe Oun ni Ọba Olugbọrọ, Oluriran ti O maa n gbọ́ gbogbo nnkan, ti O si maa n ri gbogbo ẹda, O ni imọ nipa gbogbo nnkan ti ẹmi n ṣe royiroyi nipa rẹ ati nnkan ti awọn igbaaya n gbe pamọ, nnkan kan ko pamọ fun Un- mimọ ni fun Un- lori ilẹ tabi ninu sanmọ.

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe Oun ni Olukapa ti nnkan kan ko lee ko agara ba A, ti ẹni kankan ko lee da erongba Rẹ pada, O maa n ṣe nnkan ti o ba wu U ti O si maa n kọdi nnkan ti O ba wu U, O maa n ti siwaju O si maa n ti sẹ́yìn, ati pe ọgbọ́n ti o pe n bẹ fun Un.

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe Oun ni Adẹdaa, Olupese, Oluṣeto ti O da ẹda ti O si ṣètò rẹ, ati pe ẹda n bẹ ninu arọwọ Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin gbigba Isilaamu rẹ, Kò sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe kongẹ fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

to Rẹ ati labẹ ikapa Rẹ.

Ninu awọn iroyin Rẹ ni pe O maa n da ẹni ti ara n ni lohun, O maa n ran ẹni ti wọn bò sí lọwọ, O maa n ṣi ibanujẹ lọ, ati pe ti gbogbo ẹda ba ko sinu ibanujẹ kan tabi ifunpinpin kan wọ́n maa sádi I ni dandan.

Ijọsin ko gbọdọ jẹ ti ẹnikẹni afi ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- Oun ni Ẹni ti O pe ti O lẹtọọ si i ni Òun nìkan ṣoṣo yàtọ̀ si ẹlomiran, ati pe gbogbo nnkan ti wọn bá jọsin fun yàtọ̀ si I jẹ nnkan ti wọn n jọsin fun pẹlu ibajẹ ti o jẹ nkan to dinku ti iku ati titan le ṣẹlẹ̀ si i.

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- pese awọn laakaye fun wa ti o le gbọ́ nnkan ye latara titobi Rẹ, O fi adamọ kan ti o nífẹ̀ẹ́ daadaa rinlẹ si wa lara, ti o si korira aburu, ti o si maa n fi ọkan balẹ ti o ba sadi Oluwa gbogbo ẹda, ati pe adamọ yii n tọka lori pipe Rẹ ati pe ko rọrun lati royin Rẹ- mimọ ni fun Un- pẹlu adinku.

Ko tọ fun ẹni ti o ni laakaye lati jọsin fun nnkan kan afi Ẹni ti O pe, bawo ni o ṣe maa jọsin fun ẹda ti kò pe bii rẹ tabi ti o kere si i!

Ẹni ti a maa jọsin fun ko rọrun ki o jẹ abara tabi òrìṣà tabi igi tabi ẹranko!

Oluwa wà loke awọn sanmọ Rẹ, O gunwa sori aga ọla Rẹ, O takete si ẹda Rẹ, ko si nkan kan ninu awọn ẹda Rẹ nínú paapaa Rẹ, ko si si nkan kan ninu paapaa Rẹ lara awọn ẹda Rẹ, ko ki n sọkalẹ, ko si ki n gbe awọ nkan kan wọ ninu awọn ẹda Rẹ.

Oluwa, ko si nnkan kan ti o da bii Rẹ, Oun ni Ọba Olugbọ Oluriran, ko si ẹni kan ti o jọ Ọ, O rọrọ kuro lọdọ ẹda Rẹ, ko ki n sun ko si ki n jẹ oúnjẹ, O tobi ko si rọrun ki iyawo tabi ọmọ wa fun Un; ati pe Ọba Adẹdaa awọn iroyin titobi n bẹ fun Un, ko si rọrun láéláé ki wọn royin Rẹ pẹlu ini bukaata tabi adinku.

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلنَّاسُ ضُرِبَ مَثَلٞ فَٱسۡتَمِعُواْ لَهُۥٓۚ إِنَّ ٱلَّذِينَ تَدۡعُونَ مِن دُونِ ٱللَّهِ لَن يَخۡلُقُواْ ذُبَابٗا وَلَوِ ٱجۡتَمَعُواْ لَهُۥۖ وَإِن يَسۡلُبۡهُمُ ٱلذُّبَابُ شَيۡـٔٗا لَّا يَسۡتَنقِذُوهُ مِنۡهُۚ ضَعُفَ ٱلطَّالِبُ وَٱلۡمَطۡلُوبُ ٧٣ مَا قَدَرُواْ ٱللَّهَ حَقَّ قَدۡرِهِۦٓۚ إِنَّ ٱللَّهَ لَقَوِيٌّ عَزِيزٌ ٧٤﴾ [الحج: 73-74]

{Ẹ̀yin ènìyàn, Wọ́n fi àkàwé kan lélẹ̀. Nítorí náà, ẹ tẹ́tí sí i. Dájúdájú àwọn tí ẹ̀ ń pè lẹ́yìn Allāhu, wọn kò lè dá eṣinṣin kan, wọn ìbàá para pọ̀ láti ṣe bẹ́ẹ̀. Tí eṣinṣin bá sì gba kiní kan mọ́ wọn lọ́wọ́, wọn kò lè gbà á padà lọ́wọ́ rẹ̀. Ọ̀lẹ ni ẹni tí ń wá ǹǹkan (lọ́dọ̀ òrìṣà) àti (òrìṣà) tí wọ́n ń wá ǹǹkan lọ́dọ̀ rẹ̀} (73{Wọn kò bu ọ̀wọ̀ fún Allāhu ní ọ̀wọ̀ tí ó tọ́ sí I. Dájúdájú Allāhu mà ni Alágbára, Olùborí}[Al-Hajj: 73-74].

# Nitori ki ni Adẹdaa ti O tobi yii ṣẹ dá wa? Ati pe ki ni nnkan ti O n fẹ lati ọdọ wa?

Njẹ o ba laakaye mu pe dajudaju Ọlọhun ṣẹda gbogbo awọn ẹda wọnyii laini afojusun, njẹ O ṣẹda wa lásán, Oun si ni Ọba Ọjọgbọn Onimimọ?

Njẹ o ba laakaye mu pe dajudaju Ẹni ti O ṣẹda wa pẹlu eto yii ati idamuṣemuṣe, ti O ṣe nnkan ti o wa ninu sanmọ ati ilẹ ni irọrun fun wa, pé O ṣẹda wa laini afojusun tabi ki O fi wa silẹ laisi idahun si eyi ti o pataki julọ ninu awọn ibeere ti wọn ko airoju ba wa, gẹgẹ bii: Nitori ki ni a ṣe wa nibi? Ati pe ki ni o wa lẹyin iku? Ati pe ki ni afojusun latara ṣiṣẹda wa?

Njẹ o ba laakaye mu ki o ma si ijiya kan fun alabosi, ki o si ma si ẹsan fun oluṣe daadaa?

Ọlọhun- mimọ ni fun Un- sọ pe:

﴿أَفَحَسِبۡتُمۡ أَنَّمَا خَلَقۡنَٰكُمۡ عَبَثٗا وَأَنَّكُمۡ إِلَيۡنَا لَا تُرۡجَعُونَ ١١٥﴾ [المؤمنون: 115]

(Ṣé ẹ lérò pé A kàn ṣẹ̀dá yín fún ìranù ni, àti pé dájúdájú wọn ò níí da yín padà sọ́dọ̀ Wa?)[Al-Mu'minuun: 115].

Bi ko ṣe pe Ọlọhun ran awọn ojiṣẹ ki a le mọ ìdí bibẹ wa, O si tọ wa sọ́nà nipa bi a ṣe ma maa jọsin fun Un ti a si ma maa sunmọ Ọn, ati pe ki ni nnkan ti O fẹ lati ọdọ wa! Bawo ni a ṣe maa ri iyọnu Rẹ, O si sọ fun wa nipa ibupadasi wa lẹyin iku?

Ọlọhun ran awọn ojiṣẹ lati le sọ fun wa pe Oun nikan ṣoṣo ni O lẹtọọ si ijọsin, ki a si le mọ bi a ṣe maa jọsin fun Un, ati ki wọn le mu awọn àṣẹ Rẹ ati awọn ẹ Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin gbigba Isilaamu rẹ, Kò

sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe kongẹ fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

kọ Rẹ de etiigbọ wa, ki wọn si le kọ wa ni awọn iwa ọlọla ti o ṣe pe ti a ba gba wọn mu isẹmi aye wa máa daa, yoo si kun fun awọn oore ati alubarika.

Ati pe Ọlọhun ti ran awọn ojiṣẹ ti wọn pọ gẹgẹ bii: (Nuh, Ibrahim, Musa, ati Isa) ti Ọlọhun kun wọn lọwọ pẹlu awọn ami ati awọn iṣẹ iyanu ti wọn tọka lori ododo sisọ wọn ati pe wọn jẹ ìránṣẹ́ lati ọdọ Rẹ- mimọ ni fun Un-, ti ikẹyin wọn jẹ Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-.

Awọn ojiṣẹ si ti sọ fun wa ni gbogbo ọna to han dáadáa pe dajudaju isẹmi aye yii jẹ idanwo ati pe dajudaju isẹmi aye tòótọ́ maa waye lẹyin iku

ati pe alujanna n bẹ fun awọn olugbagbọ ti wọn jọsin fun Ọlọhun nikan ṣoṣo ti ko si orogun fun Un ti wọn si ni igbagbọ ninu gbogbo awọn ojiṣẹ, ati pe ina kan si n bẹ ti Ọlọhun pese rẹ kalẹ fun awọn alaigbagbọ ti wọn jọsin fun awọn ọlọhun miiran pẹlu Ọlọhun tabi ti wọn ṣaigbagbọ ninu eyikeyii ojiṣẹ kan ninu awọn ojiṣẹ Ọlọhun.

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿يَٰبَنِيٓ ءَادَمَ إِمَّا يَأۡتِيَنَّكُمۡ رُسُلٞ مِّنكُمۡ يَقُصُّونَ عَلَيۡكُمۡ ءَايَٰتِي فَمَنِ ٱتَّقَىٰ وَأَصۡلَحَ فَلَا خَوۡفٌ عَلَيۡهِمۡ وَلَا هُمۡ يَحۡزَنُونَ ٣٥ وَٱلَّذِينَ كَذَّبُواْ بِـَٔايَٰتِنَا وَٱسۡتَكۡبَرُواْ عَنۡهَآ أُوْلَٰٓئِكَ أَصۡحَٰبُ ٱلنَّارِۖ هُمۡ فِيهَا خَٰلِدُونَ ٣٦﴾

[الأعراف: 35-36]

(Ọmọ (Ànábì) Ādam, nígbà tí àwọn Òjíṣẹ́ nínú yín bá wá ba yín, tí wọn yóò máa ka àwọn āyah Mi fun yín, ẹnikẹ́ni tí ó bá bẹ̀rù (Mi), tí ó sì ṣàtúnṣe, kò níí sí ìbẹ̀rù kan fún wọn, wọn kò sì níí banújẹ́ (35)ۚوÀwọn t'ó bá sì pe àwọn āyah Wa níró̩, tí wọ́n sì ṣègbéraga sí i, àwọn wọ̀nyẹn ni èrò inú Iná. Olùṣegbére ni wọ́n nínú rẹ̀)[Al-A'raaf 35-36].

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلنَّاسُ ٱعْبُدُوا۟ رَبَّكُمُ ٱلَّذِى خَلَقَكُمْ وَٱلَّذِينَ مِن قَبْلِكُمْ لَعَلَّكُمْ تَتَّقُونَ ٢١ ٱلَّذِى جَعَلَ لَكُمُ ٱلْأَرْضَ فِرَٰشًا وَٱلسَّمَآءَ بِنَآءً وَأَنزَلَ مِنَ ٱلسَّمَآءِ مَآءً فَأَخْرَجَ بِهِۦ مِنَ ٱلثَّمَرَٰتِ رِزْقًا لَّكُمْ ۖ فَلَا تَجْعَلُوا۟ لِلَّهِ أَندَادًا وَأَنتُمْ تَعْلَمُونَ ٢٢ وَإِن كُنتُمْ فِى رَيْبٍ مِّمَّا نَزَّلْنَا عَلَىٰ عَبْدِنَا فَأْتُوا۟ بِسُورَةٍ مِّن مِّثْلِهِۦ وَٱدْعُوا۟ شُهَدَآءَكُم مِّن دُونِ ٱللَّهِ إِن كُنتُمْ صَـٰدِقِينَ ٢٣ فَإِن لَّمْ تَفْعَلُوا۟ وَلَن تَفْعَلُوا۟ فَٱتَّقُوا۟ ٱلنَّارَ ٱلَّتِى وَقُودُهَا ٱلنَّاسُ وَٱلْحِجَارَةُ ۖ أُعِدَّتْ لِلْكَـٰفِرِينَ ٢٤ وَبَشِّرِ ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّـٰلِحَـٰتِ أَنَّ لَهُمْ جَنَّـٰتٍ تَجْرِى مِن تَحْتِهَا ٱلْأَنْهَـٰرُ ۖ كُلَّمَا رُزِقُوا۟ مِنْهَا مِن ثَمَرَةٍ رِّزْقًا قَالُوا۟ هَـٰذَا ٱلَّذِى رُزِقْنَا مِن قَبْلُ ۖ وَأُتُوا۟ بِهِۦ مُتَشَـٰبِهًا ۖ وَلَهُمْ فِيهَآ أَزْوَٰجٌ مُّطَهَّرَةٌ ۖ وَهُمْ فِيهَا خَـٰلِدُونَ ٢٥﴾ [البقرة: 25-21]

(Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná ((Ẹ jọ́sìn fún) Ẹni tí Ó ṣe ilẹ̀ fun yín ní ìtẹ́, (Ó ṣe) sánmọ̀ ní àjà, Ó sọ omi òjò kalẹ̀ láti sánmọ̀, Ó sì fi mú àwọn èso jáde ní ìjẹ-ìmu fun yín. Nítorí náà, ẹ má ṣe bá Allāhu wá akẹgbẹ́, ẹ sì mọ̀ (pé kò ní akẹgbẹ́)) (22) (Tí ẹ bá wà nínú iyèméjì nípa ohun tí A sọ̀kalẹ̀ fún ẹrúsìn Wa, nítorí náà, ẹ mú sūrah kan wá bí irú rẹ̀, kí ẹ sì pe àwọn ẹlẹ́rìí yín, yàtọ̀ sí Allāhu, tí ẹ bá jẹ́ olódodo) ( (Tí ẹ ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ ò wulẹ̀ lè ṣe bẹ́ẹ̀, nítorí náà ẹ ṣọ́ra fún Iná, èyí tí ìkoná rẹ̀ jẹ́ àwọn ènìyàn àti òkúta tí Wọ́n pa lésè sílẹ̀ de àwọn aláìgbàgbọ́) (24) (Fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe àwọn iṣẹ́ rere ní ìró ìdùnnú pé, dájúdájú àwọn Ọgbà Ìdẹ̀ra kan ń bẹ fún wọn, èyí tí àwọn odò ń ṣàn ní ìsàlẹ̀ rẹ̀. Nígbàkígbà tí A bá p'èsè jíjẹ-mímu kan fún wọn nínú èso rẹ̀, wọn yóò sọ pé: "Èyí ni wọ́n ti pèsè fún wa tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀." – Wọ́n mú un wá fún wọn ní ìrísí kan náà ni (àmọ́

pẹ̀lú adùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀). – Àwọn ìyàwó mímọ́ sì ń bẹ fún wọn nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Olùṣegbére sì ni wọ́n nínú rẹ̀)(Al-Baqarah: 21-25).

## Nitori ki ni awọn ojiṣẹ ṣe pọ?

Dajudaju Ọlọhun ran awọn ojiṣẹ Rẹ si awọn ijọ, ko si ninu ìjọ kan afi ki Ọlọhun ran ojiṣẹ kan si wọn, lati pe wọn lọ sibi ijọsin fun Oluwa wọn, ki o si mu awọn àṣẹ Rẹ ati awọn ẹkọ Rẹ de etiigbọ wọn, ati pe afojusun ipepe gbogbo wọn patapata jẹ: Ijọsin fun Ọlọhun nikan ṣoṣo- Alagbara ti O gbọnngbọn, Gbogbo igba ti ìjọ kan ba ti bẹ̀rẹ̀ si nii gbe nnkan ti ojiṣẹ rẹ mu wa jusilẹ tabi da a rú, ninu àṣẹ mimu Ọlọhun ni Ọkan ṣoṣo, Ọlọhun maa gbe iṣẹ naa fun ojiṣẹ miiran lati tun oju ọna naa ṣe, ti o si maa mu awọn eniyan pada si adamọ ti o ni àlàáfíà pẹlu imu Ọlọhun ni Ọkan ṣoṣo ati itẹle Rẹ,

Titi ti Ọlọhun fi pari awọn ojiṣẹ pẹlu Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla maa ba a-, ẹniti o mu ẹsin ti o pe wa ati ofin gbere ti o kari gbogbo ẹda titi di ọjọ igbende, eyi ti o wa pari, ti o si jẹ nnkan ti o wa pa nnkan ti o ṣíwájú rẹ̀ rẹ́ ninu awọn ofin, ati pe Olúwa si fi ọwọ sọya fun ẹsin yii lati maa ṣẹku titi di Ọjọ́ Àjíǹde.

## Eniyan ko lee di olugbagbọ titi yoo fi ní igbagbọ ninu gbogbo awọn ojiṣẹ

Ọlọhun ni O ran awọn ojiṣẹ, ti O si pa gbogbo ẹda Rẹ láṣẹ pẹlu itẹle wọn, ẹni ti o ba ṣe aigbagbọ ninu ìránṣẹ́ ọkan ninu wọn dajudaju o ti ṣe aigbagbọ ninu gbogbo wọn, ati pe ko si ẹṣẹ kan ti o tobi ju ki ọmọniyan da imisi Ọlọhun pada sọ́dọ̀ Rẹ, ko si ibuyẹ fun wiwọ alujanna laisi nini igbagbọ ninu gbogbo awọn ojiṣẹ.

Nitori naa nkan ti o jẹ dandan lori ẹnikọọkan ni asiko yii ni ki o ni igbagbọ pẹlu Ọlọhun ati gbogbo awọn ojiṣẹ Rẹ, ki o si tun gba ọjọ ikẹhin gbọ, ìyẹn o wàá níí ṣẹlẹ ayaafi pẹlu ki o gbagbọ ki o si tẹle igbẹyin wọn (awọn ojiṣẹ) ati opin wọn tii ṣe Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ẹni ti a kun lọwọ pẹlu ami ìyanu láéláé, oun

naa ni Kuraani Alapọn-ọnle, èyí ti Ọlọhun nṣọ ọ titi di ìgbà tí yoo jogun ilẹ ati gbogbo nkan ti o wa l'ori rẹ.

Ọlọhun sọ ninu Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin gbigba Isilaamu rẹ, Kò sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe konge fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

Kuraani Alapọn-ọnle pe dajudaju ẹni ti o ba kọ nini igbagbọ sí ojiṣẹ kan ninu awọn ojiṣẹ Rẹ, o ti ṣe keferi si Ọlọhun o si ti pe imisi Rẹ ni irọ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe

{Dájúdájú àwọn t'ó ń ṣàì gbàgbọ́ nínú Allāhu àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀, tí wọ́n fẹ́ ṣòpínyà láààrin Allāhu àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀, tí wọ́n sì ń wí pé: "A gbàgbọ́ nínú apá kan, a sì ṣàì gbàgbọ́ nínú apá kan," wọ́n sì fẹ́ mú ọ̀nà kan tọ̀ (lẹ́sìn) láààrin ìyẹn (150)﴾ {Ní òdodo, àwọn wọ̀nyẹn, àwọn ni aláìgbàgbọ́. A sì ti pèsè Ìyà tí í yẹpẹrẹ ẹ̀dá sílẹ̀ de àwọn aláìgbàgbọ́}[An-Nisā': 150-151].

Nitori naa awa musulumi ni igbagbọ pẹlu Ọlọhun ati ọjọ ikẹyin – gẹ́gẹ́ bí Ọlọhun ṣe pàṣẹ - a sì tun ni igbagbọ si gbogbo ojiṣẹ ati awọn iwe ti o ṣaaju, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:﴿

﴿ءَامَنَ ٱلرَّسُولُ بِمَآ أُنزِلَ إِلَيۡهِ مِن رَّبِّهِۦ وَٱلۡمُؤۡمِنُونَۚ كُلٌّ ءَامَنَ بِٱللَّهِ وَمَلَٰٓئِكَتِهِۦ وَكُتُبِهِۦ وَرُسُلِهِۦ لَا نُفَرِّقُ بَيۡنَ أَحَدٖ مِّن رُّسُلِهِۦۚ وَقَالُواْ سَمِعۡنَا وَأَطَعۡنَاۖ غُفۡرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيۡكَ ٱلۡمَصِيرُ٢٨٥﴾ [البقرة: 285]

{Òjíṣẹ́ náà (sollalāhu 'alayhi wa sallam) gbàgbọ́ nínú ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Àwọn onígbàgbọ́ òdodo náà (gbàgbọ́ nínú rẹ̀). Ẹnì kọ̀ọ̀kan (wọn) gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Wọ́n sì sọ pé: "A gbọ́ (àṣẹ), a sì tẹ̀lé (àṣẹ). À ń tọrọ àforíjìn Rẹ, Olúwa wa. Ọ̀dọ̀ Rẹ sì ni àbọ̀ ẹ̀dá."}[Al-Baqorah: 285].

# Ki ni Kuraani Alapọn-ọnle?

Kuraani Alapọn-ọnle ni ọrọ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ati imisi Rẹ ti O sọkalẹ fun igbẹyin awọn ojiṣẹ tii ṣe Muhammad, oun si ni ami iyanu ti o tobi julọ ti n tọka si ododo ijẹ anabi rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a -, ati pe Kuraani Alapọn-ọnle ododo ni nibi awọn idajọ rẹ, ootọ sì ni nibi awọn irọyin rẹ,Ati pe Ọlọhun ti pe awọn ti wọn pe e nirọ n'ija pẹlu pe ki wọn o mu iru rẹ wa koda bo ṣe suurah kan ti o jọ ọ, ti wọn si kagara lati ṣe iyẹn; latari titobi akosinu rẹ ati kikari ọrọ inu rẹ fun gbogbo nkan ti o nii ṣe pẹlu ọmọniyan ninu iṣẹmi aye ati ọjọ ikẹyin, ati pe o ko sinu gbogbo awọn pàápàá igbagbọ ti nini igbagbọ ninu rẹ jẹ dandan,Gẹ́gẹ́ bí o ṣe ko sinu awọn aṣẹ ati awọn eewọ ti o jẹ dandan ki ọmọniyan o maa rin lori rẹ nibi nkan ti o wa laarin rẹ ati Oluwa rẹ tabi laarin rẹ ati ara rẹ, tabi laarin rẹ ati gbogbo ẹda, ti gbogbo rẹ wa pẹlu ìlànà ti o ga nibi didantọ ati alaye lẹkunrẹrẹ,Dajudaju o ko eyi to pọ sinu ninu awọn ẹri ti laakaye ati awọn ododo ti imọ ti wọn tọka lori pe dajudaju iwe yii ko ṣeeṣe ki o jẹ lati iṣẹ ọwọ ẹda bi ko ṣe pe ọrọ Oluwa ẹda- mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga- ni.

# Ki ni ẹsin Isilaamu?

Isilaamu ni jijupa-jusẹ silẹ fun Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- pẹlu imu U ni Ọkan ṣoṣo, ati gbigba fun Un pẹlu itẹle, ati titẹle ofin Rẹ pẹlu iyọnu ati gbigba wọle, ati ṣíṣe aigbagbọ sí gbogbo nnkan ti wọn jọsin fun yàtọ̀ si Ọlọhun.

Dajudaju Ọlọhun gbe awọn ojiṣẹ dide pẹlu iṣẹ-ìránṣẹ́ kan oun ni: Ipepe lọ sibi ijọsin fun Ọlọhun ni Oun nikan ṣoṣo ti ko si orogun fun

Un, ati ṣíṣe aigbagbọ pẹlu gbogbo nnkan ti wọn jọsin fun yàtọ̀ si Ọlọhun.

Isilaamu ni ẹsin gbogbo awọn Anabi, ati pe ipepe wọn ọkan ṣoṣo ni ti awọn ofin wọn jẹ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ati pe ni on Ki o maa jẹ ki awọn ẹṣẹ rẹ maa kọdi rẹ kuro nibi wiwọ inu Isilaamu, ati pe Ọlọhun ti sọ fun wa ninu Kuraani pe Oun maa fori jin awọn ẹṣẹ ọmọniyan patapata ti o ba gba Isilaamu ti o si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Adẹdaa rẹ, koda lẹyin gbigba Isilaamu rẹ, Kò sóhun tó burú nínú kéèyàn máa dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, nítorí pé èèyàn ni wá kì í ṣe áńgẹ́lì tí kò lè ṣàṣìṣe.Ṣùgbọ́n nnkan ti wọn n wa lọdọ wa ni ki a tọrọ aforijin lọdọ Ọlọhun ki a si ronupiwada lọ sọ́dọ̀ Rẹ, ti Ọlọhun ba ti ri lara wa pe a tete lọ gba ododo ti a si wọnu Isilaamu, ti a si ti pe ijẹrii mejeeji, dajudaju O maa kun wa lọwọ lori gbigbe awọn ẹṣẹ miiran ju silẹ, ẹni ti o ba dojú kọ Ọlọhun ti o si tẹle ododo, O maa fi i ṣe kongẹ fun alekun daadaa, nitori naa ki ọmọniyan ma ṣe iyemeji nipa wiwọnu Isilaamu nsinyii.

i, awọn mùsùlùmí nikan ṣoṣo ni wọn n gba ẹsin ti o ni alaafia mu, eyi ti gbogbo awọn Anabi mu wa, ati pe iṣẹ-ìránṣẹ́ Isilaamu ni asiko yii jẹ ododo, oun si ni iṣẹ-ìránṣẹ́ ipari lati ọdọ Ọba Adẹdaa fun gbogbo ẹda eniyan,Oluwa ti O ran Ibrahim ati Musa ati 'Isa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba wọn- niṣẹ, Oun naa ni O ran ipari awọn ojiṣẹ Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- dajudaju ofin sharia Isilaamu wa lati pa nnkan ti o ṣíwájú rẹ ninu awọn ofin rẹ.

Dajudaju gbogbo ẹsin ti awọn eniyan fi n jọsin lonii- yàtọ̀ si Isilaamu- jẹ awọn ẹsin latara iṣẹ ọwọ ẹda, tabi awọn ẹsin ti wọn ti fi igba kan jẹ ẹsin ti Ọlọhun lẹyin naa ni ọwọ ẹda ti fi wọn ṣeré, ti wọn ti pada di adapọ ìtòjọpelemọ ìtàn àròsọ ati awọn àlọ́ ti wọn jogún, ati awọn igbiyanju ẹ̀dá.

Ṣugbọn ẹsin awọn Mùsùlùmí ni ẹsin kan ti o han ti ko lee yipada, bi o ti jẹ pe dajudaju awọn ijọsin wọn ti wọn fi n jọsin fun Ọlọhun jẹ ọkan, gbogbo wọn ni wọ́n ń ki irun wákàtí márùn-ún, ti wọn n yọ saka awọn dukia wọn, ti wọn n gba awẹ oṣu Ramadan, ronu si iwe òfin

wọn tii ṣe Kuraani Alapọn-ọnle, ó jẹ iwe kan ni gbogbo awọn ilu. Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿... ٱلۡيَوۡمَ أَكۡمَلۡتُ لَكُمۡ دِينَكُمۡ وَأَتۡمَمۡتُ عَلَيۡكُمۡ نِعۡمَتِي وَرَضِيتُ لَكُمُ ٱلۡإِسۡلَٰمَ دِينٗاۚ فَمَنِ ٱضۡطُرَّ فِي مَخۡمَصَةٍ غَيۡرَ مُتَجَانِفٖ لِّإِثۡمٖ فَإِنَّ ٱللَّهَ غَفُورٞ رَّحِيمٞ ٣﴾ [المائدة: 3]

Mo parí ẹ̀sìn yín fun yín lónìí. Mo sì ṣe àṣepé ìdẹ̀ra Mi fun yín. Mo sì yọ́nú sí 'Islām ní ẹ̀sìn fun yín. Nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí wọ́n bá kó sínú ìnira ebi (láti jẹ ẹran èèwọ̀), yàtọ̀ sí olùfínnúfíndọ̀-dẹ́ṣẹ̀, dájúdájú Allāhu ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run)[Al-Ma'idah: 3].

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ ninu Kuraani pe:

﴿قُلۡ ءَامَنَّا بِٱللَّهِ وَمَآ أُنزِلَ عَلَيۡنَا وَمَآ أُنزِلَ عَلَىٰٓ إِبۡرَٰهِيمَ وَإِسۡمَٰعِيلَ وَإِسۡحَٰقَ وَيَعۡقُوبَ وَٱلۡأَسۡبَاطِ وَمَآ أُوتِيَ مُوسَىٰ وَعِيسَىٰ وَٱلنَّبِيُّونَ مِن رَّبِّهِمۡ لَا نُفَرِّقُ بَيۡنَ أَحَدٖ مِّنۡهُمۡ وَنَحۡنُ لَهُۥ مُسۡلِمُونَ ٨٤ وَمَن يَبۡتَغِ غَيۡرَ ٱلۡإِسۡلَٰمِ دِينٗا فَلَن يُقۡبَلَ مِنۡهُ وَهُوَ فِي ٱلۡأٓخِرَةِ مِنَ ٱلۡخَٰسِرِينَ ٨٥﴾

[آل عمران: 84-85]

(Sọ pé: "A gbàgbọ́ nínú Allāhu àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún wa pẹ̀lú ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm, 'Ismọ̄'īl, 'Ishāƙ, Ya'ƙūb, àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ (rẹ̀. A gbàgbọ́ nínú) ohun tí Wọ́n fún (Ànábì) Mūsā àti 'Īsā àti àwọn Ànábì láti ọ̀dọ̀ Olúwa wọn; A kò ya ẹnì kan kan sọ́tọ̀ nínú wọn. Àwa sì ni mùsùlùmí (olùjuwọ́-jusẹ̀-sílẹ̀) fún Un) (84) (Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Islām, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò)(Aal-E-Imran: 84-85).

Ẹsin Isilaamu ni ọ̀nà ti o gbòòrò fun isẹmi ayé, ti o ba adamọ ati laakaye mu, ti awọn ẹmi ti wọn ṣe deedee naa gba a wọle, ti Ọba Adẹdaa ti O tobi ṣe e lofin fun ẹda, oun ni ẹsin daadaa ati oriire fun awọn eniyan lapapọ ni aye ati ọrun, ti ko ṣe ìyàtọ̀ laaarin ẹ̀yà kan si ẹ̀yà kan, tabi awọ kan si awọ kan, awọn eniyan ri bákan náà nibẹ, ẹnikẹni ko yàtọ̀ ninu Isilaamu si ẹlòmíì afi pẹlu ìdiwọ̀n iṣẹ ire rẹ.

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿مَنۡ عَمِلَ صَٰلِحٗا مِّن ذَكَرٍ أَوۡ أُنثَىٰ وَهُوَ مُؤۡمِنٞ فَلَنُحۡيِيَنَّهُۥ حَيَوٰةٗ طَيِّبَةٗۖ وَلَنَجۡزِيَنَّهُمۡ أَجۡرَهُم بِأَحۡسَنِ مَا كَانُواْ يَعۡمَلُونَ ٩٧﴾ [النحل: 97]

(Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere, ọkùnrin ni tàbí obìnrin, tí ó sì jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo, dájúdájú A óò jẹ́ kí ó lo ìgbésí ayé t'ó dára. Dájúdájú A ó sì fi èyí t'ó dára jùlọ sí ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́ san wọ́n ní ẹ̀san wọn)[An-Nahl: 97]

## Isilaamu ni oju ọna oriire

Isilaamu ni ẹsin gbogbo awọn Anabi, oun ni ẹsin Ọlọhun fun gbogbo àwọn ènìyàn, ko kii ṣe ẹsin Larubawa nikan.

Isilaamu ni oju ọna oriire tòótọ́ ni aye ati idẹra gbere ni ọrun.

Isilaamu ni ẹsin kan ṣoṣo ti o maa n dahun fun awọn bukaata ẹmi ati ara, ti o si maa n yanjú gbogbo awọn ìṣòro ọmọniyan, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿قَالَ ٱهۡبِطَا مِنۡهَا جَمِيعَۢاۖ بَعۡضُكُمۡ لِبَعۡضٍ عَدُوّٞۖ فَإِمَّا يَأۡتِيَنَّكُم مِّنِّي هُدٗى فَمَنِ ٱتَّبَعَ هُدَايَ فَلَا يَضِلُّ وَلَا يَشۡقَىٰ ١٢٣ وَمَنۡ أَعۡرَضَ عَن ذِكۡرِي فَإِنَّ لَهُۥ مَعِيشَةٗ ضَنكٗا وَنَحۡشُرُهُۥ يَوۡمَ ٱلۡقِيَٰمَةِ أَعۡمَىٰ ١٢٤﴾ [طه: 123-124]

